# EKO AKETE.

"EMI VIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. III. No. 119. SATURDAY, OCT. 25, 1924. FOURPENCE.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods,*

**"Specialities: Enamelware Beer. Wine. Iron Bedsteads. Ruby Plates. Rubber Beads of all kinds. Clay and Briar Pipes. Champagne. Cement. Biscuits in cases. Gun Powder. Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice. Accordeons. Piano. Padlocks. Beads etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa'ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọny fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ājàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, aṣọ iṣ'ọṣọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maṣini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin ṣipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## No. 1, LAGOS.

## OLOWO S'OKE D'ILẸ

A ni oriṣiriṣi ọja fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

A nta awọn ọja wa ni :—

**3d. 6d. 9d. 1s.**

A nṣi ilẹkun di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Satide.

*Editor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices* : 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———.o.———

ABỌ O, ALUFA AJISỌDIDUN L'OYINBO, ỌMỌ TI O T'O MỌ L'AGBO.

Ku ti Ẹni-ọwọ S. C. Phillips Alufa Alabojuto Ijọ Ṣọṣi C.M.S. ni ode Ondo kan wa ni ibi iṣẹ wa ni *Friday* ọsẹ to kọja lọ mu wa mọ pe Jagun ṣeṣẹ de s'ilẹ yi ni, o si sọ ipalẹmọ ti gbogbo Ijọ on na nṣe fun Ariya *Jubilee* ti a sọrọ rẹ ninu "*Eko Akete*" lọsẹ diẹ sẹhin; nigbati a nī niran ohun diẹ to ṣẹlẹ nigbati t'awa tirẹ ati aburo rẹ T. K. E. Phillips A-f'orin jiṣẹ Oluwa fi ṣe ọmọde pọ ni Ile-iwe kanna ti C.M.S. ni Ode Ondo niwọn ọdun mẹrinle-lọgbọn sẹhin tabi ju bẹ lọ, ẹnu ya gidigidi fun riranti ere ọmọde wa igbāni.

A gbọ pe ninu Ariya Adọta Ọdun yi, a o ṣe Akanṣe Iwe-ika-oṣu ọdun fun ọdun to mbọ (*Jubilee Calendar*).

B'o ri Ọgbẹni na, o yara ju aṣa lọ, nṣe lo ntẹ kẹkẹ-ologere rẹ fin i nipa jiju sihin ju sọhun; a si tilẹ gbọ pe o sọ oju abẹ ni'ko ninu Iwasu to wa ni Ṣọṣi Alagogo ni *Sunday* to kọja.

Ajinde ara a ma jẹ fun ọ, o sunan-sunan ṣ'ọkọ ọmọ oni'le Erin!!!

AJANAKU BABA NAMA, ERIN WO!!!

A-gba yanu ni iku Ọgbẹni James Akindele Sule ti 17, *Custom Street* jẹ loju ẹnikẹni to gbọ ni alẹ Satide to kọja, ere ni aṣaya ni, bẹbe ọrọ ọfọ nla yi tankalẹ kakiri gbogbo ilu.

O ṣe, ọkọnrin lọ! Alawada lọ! Ọlọyaya, Oninure lọ! Sule ko binu ẹru, ko binu ọmọ, A-gbede bi ọ̀fẹ́, a-mara re bi odẹ.

O d'arinako!
O d'oju àlà firi!!
O d'oko alawo!!!

A KI TI OJỌ OGUN W'ẸFỌN.

A gbọ pe awọn Aṣaju ni Ijọ gbogbo-gbo ti Enia Dudu ni Iwọ Orun *Africa* (*National Congress of British West Africa*) npete lati wa bẹ Ẹka ti ilẹ yi wo ni ọsẹ keji oṣu *December* to mbọ; diẹ ninu awọn ti o mbọ ni eyi:—Ọlọla Hutton Mills Lọya, Ọlọla Casely Hayford Lọya, Dr. Nanka Bruce lati *Accra* ati Ọlọla C. May. "Gomina" ilu *Freetown* ni Saro yio ti ilu Saro na wa pẹlu.

A tanma pe awọn Ẹka Eko yio jigiri lati gba awọn Alejo nla yi t'ọwọ t'ẹsẹ nigbati nwọn ba de.

Afara ni'ja Ẹkun.

ABỌ O, ALHAJI OṢODI.

Alhaji Bakare D. Oṣodi to lọ si Mecca yio ba ọkọ *S.S. Aba* de nijọ Alamisi. A ki Oloye Saka Oṣodi, Dısu Akiyẹmi ati M. S. T. Oṣodi Akọwe Ẹgbẹ Irawọ Oṣodi ku ipalẹmọ.

OṢE, ẸNITI O'TORI OBINRIN KAN KU ẸGBARUN RẸ TI NU U.

S. O. Ọkẹ ọkan ninu awọn Akọwe ayọwe (*2nd Class Sorter*) ni *General Post Office* ni'bi, bu nkan jẹ, o si ku ni *Wednesday* ọsẹ yi, nitoriti obinrin Adelebọ kan ti o ti n'ẹ, pada lọ s'ọdọ ọkọ rẹ, nigbati ija obinrin na ati ọkọ rẹ ti pari nikọkọ lala; jẹ pe Ọkẹ Akọwe yi m'ẹmẹ l'ẹmẹ mọ.

———

## Welcome Home.

Messrs J. H. Doherty, F. G Martains and Akin Adeṣigbin arrived from Europe on the *Waheche* on Thursday last, safe and sound.

### Si Oni'we-irohin *Eko Akete.*

Mo juba o.

Gẹgẹ bi a ti ṣe ileri pe irohin ati itan miran yio tun jade anu ṣe ni lati sọ fun awọn ti o ngbadun wa l'ọsẹ ọsẹ pe a o fi di igba miran ti aye ba ṣofo fun wa. Ẹnyin Ijọ *Brotherhood* ọro wa yi ko ba nyin wi rara, nitoripe ẹ ko fi halehale owo bẹrẹ isin ti nyin, bi ẹnyin tilẹ kọ owo ti Eleko fi ranṣẹ sadakata nyin. O ṣe fẹnrẹn si wa leti pe Ijọ Olowogbowo (*Wesleyan Olowogbowo Church*) kọ owo ti Ọba Eleko fi ranṣẹ si wọn fun adura ti arun ti o wa lode yi, bi eyi ba ri bẹ, o yẹ, o si tọ ki a bẹ ẹrọ na wo, gbogbo wa lo sa mọ pe owo ni gbongbo ẹṣẹ (*money is the root of all evils*) ati pe laisi owo ko si ohun ti ẹnikan le ṣe, nitorina a o bẹ t'ọmọde t'agba lati fi lakaye ba wa fi ọgbọn ati oye tẹle ọrọ wa.

Gẹgẹ bi oniruuru ofin ti o wa fun awọn Ijọ Onigbagbọ, a ko ro pe owo bi iru eyi ti Eleko fi ranṣẹ na tilẹ buru lati gba. Ni akoko Kọrẹnsi (*Currency Notes*) a ṣe akiyesi pe gbogbo aiye lo nlugbugbu, iba ṣe ni Ṣọṣi tabi Mọṣalaṣi, gbogbo wa si nfẹ ma jẹ oriki yi:—"Ta lo ṣe yi emi lo ṣe yi dandan" ni akoko Kọrẹnsi yi inu awọn Alufa Ṣọṣi ndun si awọn ti o nra burẹdi (*Bread*) kan ni pọnwun meji abo (*a bread for £2. 10. 0*) Aja kan fun pọnwun mẹrin (*a Dog for £4. 0. 0*) ni akoko wọnyi ko si ohun ti a ngbọ lẹnu awọn Alufa wọnyi bikoṣe (*God loveth the cheerful giver*) Ọlọrun fẹ oninudidun ọlọrẹ, o ha ṣe pe awọn Alufa wọnyi ko mọ pe ọna eru ni owo aburadi yi ṣe mbo si ọwọ awọn "Awa lo wa nbẹ." tani ninu wa to ba le fi ọwọ sọ aiya pe lilọ Ṣọṣi on lo mu ki Alufa fẹran on pupọ bikoṣe pe nkan nṣe gbẹdẹ fun.

Ni akoko Kọrẹnsi yi mo ṣe akiyesi ọrẹ mi kan ti nkan ṣe gbẹdẹ fun tobẹ ti gbogbo wa fi nwo bi ẹnipe ẹda rẹ yato si ti gbogbo wa, ani awọn agbalagba miran tilẹ sọ agba wọn nu nipa ati n fere gasi ọti gini (*gin*) diẹ mu lọdọ ọrẹ mi yi, bẹna ni ipo rẹ ni Ṣọṣi ko kere, emi *Akirimanu* papa nko kẹrẹ ninu ile ọrẹ mi yi o, nitoripe mo mọ pe agbalagba ti ko ni owo lọwọ to nfọ ni ka a akọ aja lo ngbo; nipa bayi emi papa di wọle-wọde ọrẹ mi yi, ẹnu mi sa dun pupọ, bi ọrẹ mi yi ko tilẹ fẹ gbe nkan mimu jade nigbati mo ba bẹrẹ si sọ itan oniruru yio gbe kini na jade; ẹnikeji, emi na yio wa tẹrẹrẹ tobẹ ti a fi ni oruko adape fun nkan mimu *Jarvis* ibere wa lakoko na niwọnyi *any Jarvis?* kilo mu gbogbo iwọnyi wa bikoṣe owo Kọrẹnsi.

Nko sọ pe igba buru fun ọrẹ mi yi pupọ ninu igbesi aiye rẹ nisisiyi, ṣugbọn ohun ti a fẹ tokasi ni iwa agabagebe ti o wa larin wa ni igboro Eko. Awọn agbalagba ijọhun da loni lọdọ ọrẹ mi yi? Ko si kan ṣoṣo mọ kaka bẹ ti nwọn ba ṣe alaba pade rẹ ọrọ wọn ko ju *The time is very, very hard* eyini ni akoko yi le pupọ awọn ti o nra burẹdi (*Bread*) kan ni pọnwun meji abọ, pẹlu awọn ti o nra aja kan ni pọnwun mẹrin, nibo ni nwọn wa loni, awọn ti awọn Alufa Ṣọṣi nwo bi ayanfẹ Ọlọrun nibo ni nwọn wa, ọpọlọpọ wọn npa kọrọ kiri ni loni. Saba kini mu awọn Ijọ Olowogbowo lati kọ owo ti Eleko fi ranṣẹ ko ye wa rara boya nwọn le sọ pe awọn ki gba owo fun adura gẹgẹ bi aṣa ti awọn Imale, tabi awọn miran ti ọgbọn ko to le wipe owo ati ọdọ awọn Aboriṣa ni. Njẹ bi awọn Ijọ yi ba fi sinu apo awọn alaini (*Poor fund*) eyi ko ha ni ṣe iranlọwọ fun iru awọn enia bẹ, "Awa ti fi nkan wọnni ti awa iba ṣe silẹ laiṣe; awa si ti ṣe nkan wọnni ti awa iba fi silẹ laiṣe; Ilera ko si si ninu wa" ni ọkan t'emi ẹnu mi to'lẹ ni Ṣọṣi lo mu agabagebe yi wa; Njẹ bi akọwe ile owo kan ba ṣe aṣemaṣe ti a si gbọ pe o *short* ẹgbẹta pọnwun (*£600*) ti awọn Oyinbo si ra mu ti o na owo ra ara ti Ọlọrun Alanu si yọ ninu rẹ ti o si mu bi adọta pọnwun (*£50*) ranṣẹ si Ṣọṣi fun adura ọpẹ (*Thanks Offering*) o da mi loju pe pẹlu ayọ ni awọn Alufa yio fi gba owo yi, ṣugbọn nwọn mọ ninu ọkan wọn pe owo ole ni owo yi jẹ, nwọn ko si jẹ kọ o. Ninu owo ti Eleko fi ranṣẹ yi Onigbagbọ, Imale ati awọn Abọgibọpẹ dā ninu rẹ ẹnikan ha njẹ awa de bi? Ẹnyin ara ilu ẹ ko ri iwa agabagebe bayi, ọpọlọpọ ohun miran ti awọn Ijọ iba dide si wa n lẹ ti o tọ ti o si yẹ, kaka bẹ ẹnu mi tolẹ ni nwọn fi nṣe iṣẹ. Lọna keji iwọ ọrẹ mi ti o ko gbe arede aya Oyinbo ti Ọlọrun yọnda ọmọ bi melo kan fun ti nkan ko ṣe ẹnure fun pẹlu inufo ẹdọfo kọ ni nwọn ṣe isami fun awọn ọmọ rẹ bi? Ọrẹ rẹ ti nkan ṣe gbẹdẹ fun, ti o gbe arede ti o ni obinrin bi mejila si ode kiakia kọ ni awọn Alufa yio ṣe isami fun ọmọ rẹ pẹlu? Ko tọ ki a ma de ile lagbagbaja ti o ṣe isami fun awọn ọmọ rẹ loni, eyi fihan wa pe owo ni gbongbo ẹṣẹ.

Ki nto pari ọrọ mi nko le ṣe ki nma so ti ọwọ (*respect*) ti mo ni fun Ṣọṣi Olowogbowo nitori nibẹ ni nwọn gbe tọ mi dagba, ṣugbọn iyẹn ko ni ki a ma sọ otitọ. Ṣọṣi ni Ṣọṣi sa njẹ: a gbọ ti awọn *C.M.S.* ti nwọn nfi Eku pe Ẹja nibiti obinrinbinrin npaṣẹ fa a bi ẹni pe ọdọ ẹ ni a kọ ri ẹniti o jẹ ogun, iru rogbodiyan *Stanza* koṣe *Stanza* ti ẹnu ọjọ mẹta yi, bi o ba ṣepẹ awọn Ṣọṣi Olowọgbowo ni, ọrọ yio ti yanju lailai. Mo gba fun wọn lọna iyẹn, bi awọn Alufa tilẹ nfẹ bo ọrọ mọ Alufa kan l'ara, *Society Meeting* nkọ nibiti ẹnikẹni le sọ otitọ inu rẹ (*we cannot tolerate such immorality in our Church*) a ko le gba iru iwa aimọ yi ni Ṣọṣi wa, ni iwọ yio ma gbọ l'ẹnu t'ọmọde t'agba Ijọ. Papa bi iwọ Alufa ba si nro pe iwe rẹ pọ, nibo ni iwọ yio fi ti *Lawyer* Taylor, Sanya King, William Cole, Ezekiel Davies ati awọn jakanjakan miran si? Bi Alufa kan tẹ ti ko mọ tẹ foti bi ẹni yọ

jiga ni nwọn o yọ junu, nitoripe igbagbọ ti wọn ni pe iru aṣọ ko tan l'ọja.

Ẹnyin ara mi, ẹ jẹ ki a ma fi iwa ifẹ han ni arin ara wa ka lọ ko arankan, iwa abosi gbogbo danu si okun igbagbe, ki Oluwa ki o le ran wa lọwọ bi orilẹ Ede, bi Ilu, bi Agbo-ile kankan, nigbana ni ailera yio pada si ilera fun gbogbo wa.

Mo ṣọpẹ pupọ lọwọ Oni'we-irohin *Eko Akete* fun aye diẹ yi.

Emi ni ti nyin nitotọ,
AKIRIMANU.

## FACTS AND FIGURES.

### MARCUS GARVEY'S SCHEME NOT A JOKE!

**BEGINNINGS OF AN ALL-BLACK DEMOCRACY.**

Slowly but steadily the foundation of an All-Black Democracy is being laid by a coal-black, kinky-haired, West Indian Negro (in New York City) known the world over as Marcus Garvey.

To him who studies things only on the surface, Marcus Garvey's Programme of an All-Black Republic in Africa is a wild cat scheme, a pipe dream, a fantastic, abortive and grossly fanatical enterprise which deserves to be laughed away as many times as one hears of it.

But to the observer who could see far beyond his nose and study deep below the surface, the keen observer, the student of political science and psychology, the programme drawn by Marcus Garvey is one that should arrest the serious attention and thought of both white and black people alike.

Perhaps Negroes—stay-at-home Negroes—this side of the world would not admit that the United States of America is, to-day, the centre of Negro thought the world over—but we trow not. We are apt to lull ourselves to sleep more often than not, over the pet idea that our wants and aspirations are not identical with those of the Afro-Americans or the West Indians. This may be so to some extent; but inasmuch as we are bound to face the fact that the fundamental aims at the back of the Black Man's Mind are the same everywhere, it is but wise that we recognise that inseparable link which binds one Negro and the other no matter in what empire, kingdom or republic—country or clime—each is destined to live.

Indeed Marcus Garvey might have made some mistakes as regards the details of his programme—he being a human being—but even this is a matter of opinion. What really is of primary importance is the principle underlying such scheme—a principle which, granted for the moment that Marcus Garvey fails, will yet come up again some day.

It should not be distorted into a theory that Marcus Garvey wants the whole continent of Africa—including independent Egypt, South Africa, etc.—for his Republic Scheme. No. But, at any rate, the idea of a portion in the vast African continent, entirely independent of any foreign domination, governed on modern lines for and by the Negro people is in no way offensive.

The way of men, such as Marcus Garvey is no bed of roses. Troubles have been raked against him over and over again. Liberia which in 1920 agreed and made a Treaty to the effect that Marcus Garvey's men are welcome in Liberia has now turned round to act counter to such Treaty.

And Liberia of all nations?—Well might Garvey exclaim in the language of Shakespear: *Elu Brute?*

Evidently foreign agency is at work to prevent the practicability of Garvey's object—an object which people here, in their ignorance, are prepared to laugh away as a big joke.

Says *The Daily Telegraph*:—

"...Despite a'l that is said against him (Garvey) the ovation he received to-day when the Convention resumed shows that he still retains the affection and even the confidence of his coloured friends.

"Garvey declares that there is some mistake about Liberia which will be corrected later, and in the mean time he urges that there are other places in Africa where coloured folks are welcome "and where a chance exists to *establish a great base of Negro Civilisation.*" He is now in touch with Empress Zauditu of Abyssinia..."

Such is the position of Marcus Garvey and there is no level-headed Negro who in his heart of hearts does not agree with the principle advocated by him notwithstanding difference in details.

ADEKANBI.

### ABỌ O, ỌMỌ OLOJIJERO ANAKORU.

A dupẹ lọwọ Edumare ti o mu Ọgbẹni Olorẹ wa J. H. Doherty, Oke lẹhin Ijero de lati ọna ajo rẹ si i Ilu Oyinbo ni alafia. Kabọ o, ọmọ Ọwajero, ku ewu ọna. Ki ibukun Ọlọrun Olodumare ki o ma wa lọna rẹ gbogbo. *Amin.*

Awa ni,
IJERO UNION SOCIETY.

### RESOLUTION.

The Nigerian National Democratic Party in General Meeting assembled this 18th day of October 1924 have unanimously passed the following important Resolution. 2,468 members present at the Glover Memorial Hall:—

RESOLVED:—That in view of urgent necessity for a continuity of policy at this stage in the administrative history of Nigeria when this important Dependency is enjoying internal peace and is about to enter upon a period of progressive development and commercial prosperity, this community views with alarm and regret the present decision of the Secretary of State to transfer almost simultaneously on promotion to other Colonies, His Excellency Sir Hugh Clifford and Sir Donald Cameron, the two highest Executive officers who are thoroughly conversant with Nigerian Affairs, and this community in the circumstances expresses the anxious hope that His Majesty's Principal Secretary of State for the Colonies may be graciously pleased to consider the advisability of retaining the valuable services of Sir Donald Cameron in succession to Sir Hugh Clifford as Governor of Nigeria.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, OCT. 25, 1924.

## KÚKÚ ṢIKA GBÕN, ORE KO SI LỌLA!!!

Bayi ni awọn Asun-rárà kan ni igba lailai mã nsábà nkọrin, ti nwọn si mã nfi ilù gbe e; irufẹ orin yi si fi iwa ikà ti o wọpọ lãrin awọn kan ni'lẹ Yoruba han; bi Lagbaja ṣeṣi ṣẹ Tẹ̀màdò, kàkà ki ẹni yi jẹki awọn àgbàgbà pari ija na, nṣe ni Lagbaja na yio tutọ s'oke, ti yio f'oju gbà a, ti yio si mã leri õgun ti yio fi ṣe ọmọ-ẹlakeji rẹ leṣe; bi ko sọ ọ ni õgun ẹ̀tẹ̀, o le fi oruka, ẹrẹ na 'ka si i loju ti yio si mu oju onitọhun fọ patapata laisi atunṣe; bi ko si ṣe eyi ẹ̀wẹ̀, o le sọ ọ di arọ apapandodo nipa sisõ rọ̀ ni ẹ̀wọ̀n õde; bi o si ṣe ọrọ obinrin lo da wọn pọ kẹ, àgàgà, Lagbaja yi ri "iku ọkọ tòròmọ́" niyẹn; o di ki o ma ṣọ ọkọ-lobinrin rẹ na lọwọ lẹsẹ ki ọwọ rẹ le tẹ ẹ; bi o ta a ti l'ogi, o le fọ l'ẹkọrọ: ngbọ, iwọ ti a ti nfi ogun Magun loriṣiriṣi ọna wa kiri, ti o si jaja bọ lọwọ ero-ina yi, o le gbagbe irufẹ ewu ti o la kọja baun? Bẹ̃ ẹniti o nwa ẹmi ẹnikeji rẹ lati gba yi ko ma le da eṣinṣin tabi "Larinka to nda ile ru" o.

A ko sọ pe a da awọn ti nwọn nṣe laifi bayi nipa hihu iwa aitọ si obinrin olobinrin lare rara, Ewọ̀, ṣugbọn ohun ti a nsọ nipe kini ṣe ti iru awọn ẹni bẹ̃ ko le fi ija f'Ọlọrun ja f'ọwọ l'ẹran!! kaka ki nwọn i jẹ apania ọsangangan nipa riran ẹnikeji wọn sọrun airotẹlẹ, bẹ̃ ẹniti a pa ni apafọn bẹ̃ kòtò tirẹ nikan ni yio di ni sàrẽ, ko ni di ti ẹniti o ṣe on lọṣẹ bayi.

Dajudaju, a o ri ẹniti yio dahun pe Mi o lara rẹ:" bẹni; irufẹ ẹni bẹ̃ ko le lara iwọsi, ṣugbọn o lara ki on jẹ Apania ati Agbẹmi-enia niwaju Olodumare!!! kini tilẹ ṣe ti o jẹ pe õgun ika ni awọn kan nma ri yọ si? Ko si bi ẹlomiran ko ti le lerileka ọna buburu yi to! ṣugbọn ẹ̀gẹ̀ wo lo yẹ Oluwarẹ? O di ẹmelo ni irufẹ ẹnibẹ sun ikaka nijọkan ki o si ronu pe ki on lo ọgbọn õgun on ti on mọ yi si ọna rere, bi biba obinrin ṣ'ãjo ọmọbibi, bi wiwa ọna ti ọkọ Ejinrin le ma fi kùn lọ bi arirà loju omi Langbasa titi yio fi de ọja Ejinrin, dipo igbokun ti a nta bi o ba jẹ pe atẹgun ṣi, irufẹ ọna ti awọn ọlọkọ wa ti ngba lati ọjọ nami nnalẹ titi di oni; bi egbogi bibọ lọwọ Ajakalẹ arun, iru eyi ti o ti nṣe Eko bi ọṣẹ ṣ'oju lati iwọn óṣu melo yi wa? Agbẹdọ. Ero awọn Enia Dudu miran ko lọ si ohun ti a wi yi. Ki a sa fẹ Lamọrin tabi Lakaṣegbe kù ni oke ẽpẹ̀ fun ẹṣẹ ti o jẹ pe boya on papa ti ṣẹ ẹlomiran ri, ṣugbọn ti irufẹ eniyẹn jẹ "Ẹru" Ọlọrun ti o si m'oju kuro, kàkà ki o ni ẹjẹ ẹnikeji rẹ lọrun; ọrọ ribiribi leyi, a si nfẹ ki ẹnyin ọkawe wa yẹ ẹ wò; iwa ika ati iwa ogbojú l'ogun sọ'mọ Ajẹ-ni'ko, ki ngbe ilu ti o ba laju ga; njẹ a ko ha mọ ọgõrọ enia ti pupọ ninu awọn ọmọ Anabi Adamọ ti ran lọ si ilẹtẹ ile iku, tabi ti nwọn ti sọ di ràyiràyi nipa apa s'aye ti a pa wọn? Ẹsọ ki o to awọn irufẹ enia bayi, a ti kuro ni orilẹ-ede ti a o ma ka iku pupọ enia si lọrun nipa "õgun dudu inu àdó" ti ẹlomiran ji-ngiri si, ti oju kĩ si ti awọn miran lati ma ṣe kubẹkubẹ si.

Bi o ri ẹlomiran bi o ti nlọgun gbẹ̃ ẹ ni Ṣọṣi ni akoko orin kikọ, tabi bi o ti nba búrúbúrú ninu irun-kiki ni Mọṣalaṣi, ikà inu rẹ si alakeji rẹ ju ti Kẹtẹkẹtẹ lọ: "Amòkun ṣ'ole, bi Ọba aiye ko ri ẹ, t'ọrun nri ẹ," owe Yoruba ni. Nijọ melo ni a o ṣe eyi gba?

Ki Baba maṣai mu ki irufẹ awọn oniṣẹ-ẹṣẹ bayi warìrì fun itumọ orin yi :—

K' Oṣikà mura si'ka
B' o pẹ titi w'a ba'ka rẹ lọrun,
K' Oṣika mura si'ka
B' o pẹ titi w'a ba'ka rẹ lọrun.
Ẹ ṣõgun fi gbẹ'mi
Fi gb'ẹmi o,
Ẹ nyọ si'wa ina
Ẹ ṣ'õgun fi gb'ẹmi
Fi gbẹmi o,
Ẹ nyọ si'wa ina
( Igi ma da )
K' Oṣika mura si'ka
B' o pẹ titi w'a ba'ka rẹ lọrun !!!

## KẸKẸ NIWAJU, ẸṢIN LẸHIN.

[ *Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Ero Ijọba lati gba ẹdẹgbẹrin ékà ilẹ, (*700 acres of land*) ni Yaba, lati kọ ẹgbẹrun ile si, lai ti mọ awọn tani, tabi ara adugbo wo li Eko, ni a o ko lọ sibẹ, dabi igbati enia fi Kẹkẹ ṣiwaju Ẹṣin.

Nigbagbogbo ni a ngbọ wipe, Eko ha, Eko ha gadigadi. A ko jiyan wipe bẹni, tabi bẹkọ; ṣugbọn pẹlu gbogbo aroye yi, Ijọba koi fi ọjọ kan sọ fun wa titi di oni-oloni wipe, adugbo bayi, adugbọ bayi ni enia ibẹ pọ pupọ ju iye enia ti o ni lati gbe ibẹ lọ. Kaka bẹ, Ọkọ-elefi kan ko nde lati Ilu Oyinbo lai ko ọpọlọpọ Oyinbo wa si ilẹ yi fun iṣẹ, bẹni Eko ha pupọ!

Loni, Oyinbo pọ tobẹ gẹ ni ibi iṣẹ Ọba ti o jẹ pe ori wọn ni ogidinleje owo ti Ijọba iba fi tun ilu ṣe nrun si. Owo Ibode (*Custom Duty*) nikan, lai ka owo iwe lori ọkọ wete, lori igi gẹdu, tabi owo ti Kotu ngba lọwọ awọn ẹlẹjọ, ati oniruru ọna miran ti Ijọba fi nri owo bi ẹniti o nda ẹda, to lati sọ Ijọba di ọlọla, ti ko ba si inakuna.

Gbogbo ere ti nwọn iba jẹ lori iṣẹ ti Reluwe (*Railway*) tabi Ọkọ-ilẹ nṣe t'ọsan-t'oru, faka-fiki, faka-fiki li ojojumọ, lati Ido titi lọ de Kano, titi de ijanọ Baro, Jos, Naraguta, Port-Harcourt, Enugu, ori-sisán owo iṣẹ Oyinbo, ori owo Ọkọ wọn ni o nfẹrẹ tan si.

Enia Dudu ko ṣai ri gba ninu rẹ nitotọ, ṣugbọn eyi dabi erun akara, lati ori tabili olowo, ti Lasaru njẹ ni ọjọ kini.

Lẹhin ti awọn Oyinbo onisẹ Ọba ba ti gba owo oṣu tan, ẹlomiran ngba ọgorun pọnwun l'oṣu, tabi ju bẹ lọ; lai ka *Duty Pay* tabi èni, gẹgẹ bi èni akara, lori owo oṣu, ẹlomiran ngba ogun pọnwun l'oṣu fun *Duty Pay* yi, ti nwọn ba si ni lati lọ si idalẹ, bi Ibadan, tabi ibomiran, lati ṣe iṣẹ bi oṣu kan pere nibẹ, lẹhin ti nwọn wọ Ọkọ Reluwe li ọfẹ tan, pẹlu ile ọfẹ ni Ibadan; lẹhin ọgọrun pọnwun owo oṣu, pẹlu èni *Duty Pay* ogun pọnwun, pọnwun kọkan ojumọ ni a o tun san fun wọn pẹlu, titi nwọn o fi pada de ibi iṣẹ wọn pataki ni Eko tabi Ebute Mẹta.

Lẹhin ti pupọ ninu wọn ba ṣe irã tabi õraye ọdun kan ni ilẹ yi lori Enia Dudu ti nwọn npe ni Niga (*Nigger.*) nwọn a mu ọna Ilu Oyinbo pọn lati gba isimi oṣu mẹrin tabi marun (alalikua, *Hotel* ni ọpọlọpọ wọn ngbe nibẹ,) ilu ni yio san owo Ọkọ alọ, owo Ọkọ abọ; ti yio si tun ma san owo oṣu wọn perepere lọhun titi nwọn yio fi tun pada wa si ilẹ yi lati paṣẹ fun "Niga."

A ko wipe gbogbo Oyinbo ni olõrayè, agbẹdọ! Ṣugbọn ti a ba to Oyinbo jọ ni mẹwa-mẹwa ni ibi iṣẹ Ọba, boya ni a le ri mẹta-mẹta pere ninu wọn ti o nṣe iṣẹ a-ṣe-kara; pataki iṣẹ awọn ti o ku ni lati ma fi ọwọ si Iwe-iṣẹ ti Enia Dudu ba ti ṣe yọri.

Aiye ti pupọ ninu Oyinbo onisẹ Ọba njẹ, ati ipo ti nwọn nlo, Oyinbo onișowo ko ri idaji aiye na jẹ, tabi idaji ipo na lo; bẹni awọn onișowo li o dabi ori, onisẹ Ọba, ati Oyinbo, ati Enia Dudu li o dabi àgbọn, ori li o si duro fun àgbọn mu'mi.

Pẹlu gbogbo inawo bi ọba Pẹnlẹpẹ a-l'owo-ma-mọ-nọ ti Ijọba nṣe yi, ọpọlọpọ iṣẹ miran wa ti ko ju eyiti Akọwe Enia Dudu kanṣoṣo le ṣe lọ, Oyinbo meji tabi mẹta ni a o ba ni idi rẹ, ti nwọn *busy doing nothing.*

Ki Akọwe Enia Dudu miran to le ri pọnwun mẹfa, ṣile mẹtala pẹlu kọbọ mẹrin gba lowo Oba li oṣu, a ni lati kọkọ dan a wo ninu ẹkọ Iwe-mimọ, ki o si k'ogo-ja ninu idanwo kan ti a npe ni *Higher Division Clerical Examination.*

Bawo ni iba ti dun to, bi o ṣe wipe Oyinbo pẹlu Enia Dudu ni a ndanwo pọ bayi, Oyinbo miran iba bolẹ pirapira.

Iwa buruku kan ti Ijọba nhu nisisiyi ni aṣa ki a ma fi ogede awọn ọdọmọdekunrin wa si "ipo Oyinbo" laibikita, nigba pupọ, fun awọn agbalagba aṣiwaju wọn nibẹ; papa nigbati o ṣe wipe Ijọba papa na ni o lo pupọ ninu awọn agbalagba wọnyi lati kekere titi nwọn fi di arugbo, ti irun funfun nyọ li ori wọn.

A mọ wipe diẹ ni iwe agbalagba miran fi ju ti Akọwe alagbọn lọ, ati wipe agbalagba miran ko fẹ ilọsiwaju ọmọde rara, afi iṣubu rẹ. Ṣugbọn gbogbo agbalagba kọ ni ko mọ iwe, gbogbo wọn kọ li o ni ika. Ikà ọdọmọde miran tilẹ buru ju ti Ibakasiẹ lọ.

Nigbakugba ti a ba ngbọ irohin ilọsiwaju ọmọde ni ibi iṣẹ Ọba, nṣe ni inu wa ndun lọpọlọpọ, o si jẹ ohun ibanujẹ lati ri wipe, nisisiyi ti iṣẹ Oba san diẹ, awọn agbalagba ti o ti nba wọn jiṣẹ-jiya lati ọdunmọdun yi wa ndi ẹni itanu; nitori kini? Ko nṣe wipe nwọn ko mọ iwe, ko nṣe wipe nwọn ko mọ iṣẹ, bikoṣe wipe nitori irun funfun tá-tà-tá nde ori wọn. Bi a ti nfẹ ilọsiwaju ọmọde, bẹni a nfẹ ti agbalagba pẹlu; jẹ-ki-njẹ l'o nmu ayo dun.

Nipa ọrọ ti awọn Oyinbo ti a nsọ, inakuna owo ti Ijọba nna lori wọn, ko le jẹ ki owo ṣẹku pupọ lati fi tun awọn ilu ti o nmu owo yi wa ṣe, gẹgẹ bi o ti tọ, ati bi o ti yẹ. Ogo ni Ijọba ndaba lati ya Munisipa ni ẹgbẹrun ọna okõle-rugba pọnwun £220,000 fun kikọ ile ati rira ilẹ ni Yaba pẹlu èlé (*Interest.*) bi ẹni wipe Ijọba ọtọ, Munisipa ọtọ, tabi, bi ẹni wipe atunṣe ilu ko kan Ijọba to gẹgẹ bi o ti kan Munisipa, bẹni arumọjẹ ni gbogbo rẹ.

Nitotọ, Munisipa ni lati duro gedegbe fun ara rẹ, Ijọba si ni lati duro lọtọ bakanna; ṣugbọn Munisipa ilẹ yi ha ri bẹ? Bi otitọ ọrọ ba de 'lẹ, ki irọ s'alọ. Ko si Munisipa atata ni ilẹ yi, lasan ni ilu ni Aṣoju mẹta nibẹ! Kareta lasan ṣa ni a fi nbo ara wa loju! Ẹka (*Branch*) ibi iṣẹ Ọba, ni

Ṣabu owo Omi, owo Ẹran, owo Tanwiji, owo Mọto ti a npe ni Munisipa nisisiyi.

Nigbati Arun Ekute de si Oko Awo, idamu de si Ijọba, rogbodian wọ ilu. Boya nigbana ni Ijọba to ṣẹṣẹ mọ wipe adugbo na le mu ailera wa, ati wipe enia pọ nibẹ ju bi o ti yẹ lọ. Lehinna, aisan yi de Idumọta, ati adugbo miran: a si dupẹ wipe, Baba np'ẹtu si i nisisiyi.

Ni akoko aluba yi, ni ero na sọ si Ijọba l'ọkan l'ojiji lati ra ẹdẹgbẹrin eka (*acre*) ilẹ ni Yaba, lati kọ ẹgbẹrun ile sibẹ, lati la ọna ti o gboro daradara, lati fa omi sibẹ, ati Atupa Ṣango (*Electric Light*).

Owo ti Ijọba ya si ọtọ lati fi ra 700 *acres of land* jẹ ẹgba mẹdọgbọn pọnwun £50,000, nigbati a si fi iṣiro si owo yi, a ri i pe o kere pupọ; ṣugbọn Ijọba wipe ẹniti owo ti Ọba ba san fun ile tabi ilẹ rẹ ko ba tẹ lọrun, o le pe Ijọba lẹjọ, Ijọba yio si tẹle idajọ Kotu.

Njẹ ko ha san ki Ijọba kuku pinnu lati san owo daradara ti yio mu itẹlọrun wa fun ẹniti o ba fẹ ta ilẹ tirẹ, ju ati fi aye silẹ fun ẹjọ pipe lọ. Ọpọlọpọ enia ni ko r'aye lati ma para Kotu, ki o ma lọ, ma bọ, bi ilẹkẹ idi Aṭiro, laisa inir aowo ipẹjọ, owo Loya, ati inawo miran ti o mu da ni. Ṣugbọn boya Ijọba yio ṣe ofin lati fun ẹnikẹni ti o ba pe on lẹjọ nitori ilẹ Yaba ni anfani ati pe ẹjọ na l'ọfẹ, ki Ijọba si gba ojẹgẹ ati san owo Loya oluwarẹ, yala oluwarẹ jare tabi o jẹbi oba. Ti o ba si di ọran *Privy Council* ni ilu Oyinbo, ki Ijọba nikan san gbogbo inawo t'ọtun, t'osi.

Nitori lẹhin ti Wọnlẹ-wọnlẹ ba ti yọ ṣile meji meji tirẹ lori pọnwun kọkan ti Ijọba ba san, o ṣoro ki onilẹ to ri owo kan ya sọtọ mọ fun inawo Kotu lati ba Ijọba ro ẹjọ.

Ẹgbẹrun ile ti Ijọba fẹ lati kọ si Yaba, ọgọrun pọnwun (£100) pere ni a o fi kọ ikọkan, ile ọpa ni yio si jẹ.

Ọgọrun ile opa. Ati kọ ọ, ko to ati ri ẹniti yio gbe ibẹ. Ati ara Oko Awo, ati ara Idunmọta, ati ara Idunmagbo ati adugbo miran, ti Dokita ọba ko lọ si Ikoyi nwọn ti da wọn silẹ nisisiyi, nwọn si ti pada bọ si Ile wọn. O si da wa loju gbangba pe, lagbara Ọlọrun, ki a to ri osẹ melo kan si i, arun ekute yio lọ si okun igbagbe.

Njẹ lẹhin ti arun ekute ba ti lọ tan, awọn ara adugbo wo l'Eko ni Ijọba yio ha ko lọ si ẹgbẹrun Ile ọpa ti nwọn ba kọ si Yaba?

Ohun ti Ijọba ni lati kọkọ ṣe ni *Town Planning Scheme*, lati mọ adugbo ibo lo ha to nfẹ atunṣe, ti enia ibẹ si pọju bi o ti yẹ lọ l'Eko, ti nwọn le lọ gbe Yaba fun igba diẹ titi a o fi ṣe gbogbo atunṣe to tọ ni adugbo rẹ, ki o to pada wa ile. Bi bẹkọ, kẹkẹ ni Ijọba fẹ fi siwaju ẹṣin yẹn.

Lati tubọ la ọrọ ti a nsọ. Njẹ ki a wipe adugbo emi Atari Ajanaku lo ha ju, to si nfẹ atunṣe, Ijọba ha'ro pe Atari Ajanaku yio gba ojẹgẹ lati gbe ile ọpa nigbati Oyinbo *Fitter* laṣan laṣan to nṣiṣẹ l'ogba Loko ni Yaba kanna, ngbe ile pẹtẹsi ti a fi ogulutu kọ? Agbẹdọ! Kamari!! Kamari!!!

O yẹ ki Ijọba kọkọ mọ irufẹ enia wo ati ipo ẹniti nwọn fẹ kọkọ ko lọ si Yaba, ki nwọn to bẹrẹ si lọ kọ ile sibẹ. Enia kan ha jẹ daba pe ki Ẹniọwọ bi *Bishop* Oluwọle, tabi Ọlọla Lọya Shyngle, tabi Dokita Randle, tabi Ọgbẹni Henry Carr ati awọn jakanjakan miran wa lọ gbe ile ọpa ti a fi ọgọrun pọnwun pere kọ si Yaba?

A tanma pe bi a ba fi iru iwọsi bayi lọ Ọlọla Kitoyi Ajasa papa to tilẹ jẹ pe ohun gbogbo ti Oyinbo ba ṣe lo nrọ l'ọrun, ariwo yio ta.

Owo Ilu ti a fi kọ ọpọlọpọ Ile ti agbawo (*Stewards*) ati kuku (*Cooks*) Oyinbo ngbe ju ọgọrun pọnwun lọ, owo ile Mọto (*garage*) miran ju ọgọrun pọnwun lọ; sibẹsibẹ, ile ọpa ọlọgọrun pọnwun ni Ijọba ro pe o dara fun ẹnikẹni ninu wa. Ewọ!

A lọ wo Ilẹ kan ni Yaba laipẹ yi, a ri bi aṛẹfẹ tabi iji ibẹ ti le to, ati ewu to wa fun ẹgbẹrun ile ọpa ti Ijọba npete lati kọ sibẹ bi ina ba ṣeṣi bẹrẹ si jo ile kan nibẹ.

Ninu ohunkohun ati ọnakọna ti Ijọba ba fi le tun Ilu ṣe daradara, awa wa nibẹ; ṣugbọn awa ko si nidi ki a fi Kẹkẹ ṣiwaju Ẹṣin, a ko si nidi kikọ ile ọpa, a ko si nidi ki Ijọba ya Munisipa lowo pẹlu ele fun atunṣe Ilu, a ko si nidi ki Ijọba maṣe san owo to jọju fun ẹniti o ba ta Ile tabi Ilẹ tirẹ fun wọn, a ko si nidi ki a sun onilẹ si inawo apapandodo lati pe Ijọba l'ẹjọ si Kotu, nigbati ko nṣe pe nwọn lẹ iwe mọ Ile tabi Ilẹ wọn lati ta a ni gbanjo fun Ijọba. Ko yẹ ki enia gbe'le gb'ọfa, lai r'ogun.

SIR DONALD CAMERON.

Lakaye, ọgbọn, otitọ inu, ati ikorira alaṣeju, jẹ ẹbun pataki ti Anọbi fi ta Ọlọla Donald Cameron l'ọrẹ. Eyi lo si jẹ ki t'ọmọde, t'agba, ma yọ mọ ṣẹṣẹ bi igbati ọmọde nyọ mọ ẹiyẹ. O nlọ si ilu Tangayika nisisiyi, a si tanma pe on ni yio rọ'po Gomina wa, nigbati o ba fi iṣẹ silẹ gẹgẹ bi wahala ti a nṣe nipa rẹ nisisiyi. A o tun sọ diẹ nipa ọrọ ọlọla Donald Cameron yi nigbati ọwọ ba di lẹ, ati gẹgẹ bi o ti d'oju ti awọn ọlọtẹ to ni ki Ijọba wa, wa Eleko ati awọn isangbe re kuro ni Ilu nijọsi, ọpẹlọpẹ Dr. Magnus Macaulay ati Ọgbẹni Josiah Henryson Doherty.

---

Mrs. Abimbọla Gibson, abọ o! pẹlu ayọ pupọ ati inu didun ni a fi ki iya afin wa yi kabọ ilu Oyinbo. Alafia kọ ni ẹ de bi?

Bẹ gẹgẹ ni a si ki Ọgbẹni J. H. Doherty, F. G. Martins, Akintunde Adeṣingbin ati omidan Ayọ Wright ati Flora Doherty kabọ pẹlu. Ẹ ku ewu ọkọ.

Emi ni tiyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## FROM THE EDITOR'S OFFICE WINDOW.

### Mr. E. A. Alawode promoted.

Congratulations to Mr. E. A. Alawode of the P.W.D. Kaduna, for being promoted to the grade of an Assistant Chief Clerk in his Department, during the current month.

### A School-master's "Coming-of-age."

The many friends of that silent but shrewd and hard-working pedagogue, Mr. S. A. Thomas, Senior Tutor C.M.S. Grammar School, Lagos, will learn with surprise not unmixed with real pleasure that Mr. Thomas attained his majority in the teaching profession in the same school, on June last.

### Many Happy Returns !!!

Mr. John Augustus Tade Bright, late of The Hon. J. Egerton Shyngle's Office and eldest son of the late lamented Rev. J. A. Bright and younger brother of Messrs. D. Ayo and E. A. Olu Bright attained his 28th birthday on Thursday last, the 23rd inst.

Many happy returns of the day !

### Messrs. A. Kessler to the Fore.

We learn that the record-breaker Coffin in which the body of the late Mr. James A. Sule is now taking its long rest in the lap of Mother Earth, unsurpassed in artistic workmanship, design and finish in the annals of "coffin world in this country" was ordered for our good friend ere his decease, by the local branch of Messrs. A. Kessler of Labinjo Lane.

Thousands who flocked to see the "Narrow-bed" when the corpse was being borne gently and in horse-trot fashion to God's Acre in Mr. W. A. Dawodu's new Motor-Lorry fitted for the occasion, were wonder-struck at its magnificence ; the coffin, it is stated cost the deceased £45 C.I.E. to these shores.

We congratulate the Firm on this piece of commercial venture.

### Mr. D. J. Thomas.

Mr. D. J. Thomas of the P.W.D., Lagos, popularly known as "D. Jibs" on account of his unrivalled knowledge of M.P's sorting in the Fileroom, who has been on a three-month leave of absence will resume duty on the 5th *proximo.*

---

### MACHINATION MEDALLISTS.

Ye laurel won in medacity,
Under the canopy of high places
Whirling your venomous tongue to destroy,
Those by sheer FATE lower situated.

Ye are the pillars of all you survey,
In this terrestrial abode
Relying solely on unquestionable dealings
To the detriment of Allah's creations

Pause for a moment and ponder.
What extent of retributive justice,
On your infidel issues and kith and kin
To your utter disgrace eternal

Like Pharaoh of old ye are hardened,
Yet be assured evil doers shall never escape.
The wrath of the benevolent Almighty,
Which, undoutedly, shall be the reward.

JOVE.

## LABARI LATI ABẸOKUTA.

Ni ọjọ *27th* oṣu *September* ti o kọja ni Alake ṣe ajọdun ẹkẹrin ti o gun ori oye. O ṣe isin Idupe ni *Church St. Peter* ni Ake gẹgẹ bi iti ma ṣe. Pẹlu awọn (*Member Council*) Igbimọ rẹ, ni ẹrọ kan, gbogbo *Church* na ni o kun, lẹhin isin gbogbo Ẹgba tẹle e lọ si ile nibiti nwọn gbe jẹ orisirisi onjẹ ati orişi ohun mimu. Ko ni fẹnu sọ. Gbogbo awọn ọmọ Ile-ẹkọ ni o lọ si ile rẹ gẹgẹ bi nwọn ti ima ṣe, o si ta wọn lọrẹ pẹlu. Kabiyesi o, ki Ade ko pẹ lori, ki Bata ko pẹ lẹsẹ o.

Ni ọjọ 2 oṣu *October* yi ni a şi Ile-ẹkọ giga ti awọn ọmọbinrin ti Ijọ awọn *Bapist* ti a kọ si idi Aba. Isoko kan si oko Madam Şubuola Ẹgbẹrongbe, eyiti Gomina Agba lati Eko wa fun ariya, ọjọ na ko ṣe f'ẹnu kan. Alake ati awọn Ọba, awọn Igbimọ, awọn ẹgbẹ Kila, ati gbogbo Ẹgba ni o lọ pade Gomina Agba. Lẹhinti Gomina ti pari şişi ile yi tan, ti o si ti pada si Eko, gbogbo Ẹgba ba Alake lọ si ile fun ipanu. Ẹniti o ṣe iṣẹ Ile-ẹkọ na ni Mr. Thomas Litchfield, Oyinbo ti o jẹ oga iṣẹ ni *Blaize Memorial Institute* ni ilẹ yi. A gbọ pe awọn ọmọde yio bẹrẹ si kọ ẹkọ ni Ile-ẹkọ titun yi titi ẹhin ọsẹ.

Ni ọjọ 12 oṣu *October* yi, a ṣe Igbeyawo kan ni ile isin *St. Peter* Ake, larin Mr. Hezekiah Oyenẹkan Lufowora ati Winifred Joana Adekanla. Ọkọ jẹ aburo Dadd. Lufowora ti Igbein, o si nṣe iṣẹ l'Eko, Iyawo jẹ ọmọ Mr. Oriade Şolọtan ti Wasimi, Ake. o si jẹ oga *Cabinet Maker* ni ilẹ yi, Iyawo ọjọ na dun o ni arẹnrẹn, lẹhin ti a kuro ni *Church* (nitori agogo meji ọsan ni a fi Igbeyawo si) gbogbo awọn abẹyọ Iyawo ba Iyawo lọ si ile, nibiti baba iyawo ti pese ipanu fun, gbogbo awọn ti o wa ṣe ẹyẹ Iyawo. Ogboni Feyişara Şopein ni o ṣe Alakoso ibi Iyawo na. A ki awọn oniyawo nwọn ku inawo Iyawo o. Iyawo a rẹ o.

Ni 13 oṣu *October* yi ni ọjọ ti nwọn nna ọja Ọba Oko, a gbọ pe *Motor* ti o nko eru meji tẹrẹ fi ori sọ ara wọn, ohun ti a gbọ pe o mu eyi wa ni pe *Motor* kan nti Abẹokuta lọ si Oko, ekeji mbọ lati Owode, eyiti o nti Abẹokuta bọ ko fẹ ya fun ekeji, igbati o ri pe on bọ sinu ewu tan ni o to ya, yiya ti o ya yi wa ṣe jamba fun awọn ti o joko labẹ isọ, ko ma ṣe pe nwọn sare dide nibiti wọn joko si, iṣe ni iba wo wọn molẹ womuwomu.

A gbọ pe o fọ igba atẹ Ayaba kan (Ọşilẹ) o si fi diẹ ninu aşọ ti o nta şofu, a gbọ pe ọran na yio de Kotu, nitori iwa ta lo ma mu mi ni awọn oni *Motor* yi nwa *Motor* wọn lọna Oko, fayara ni.

Ni ọjọ 14 oṣu yi kanna, oni *Cycle* kan kọlu ìya agba kan ti o ru apẹrẹ Elubọ l'ori: iya agba yi ṣubu lu ilẹ, niwọn iṣẹju meji ko le dide, igbati o jaja dide, rẹrẹ nwọn ko ara wọn lọ si Ake ni ile Ọlọpa nibiti awọn Ọlọpa si wi fun wọn pe ọjọ mẹjọ loni nwọn o tun ọran wọn ro, o to akoko ti awọn enia wa iba mọ ibiti Ijọba ni ki a ma pọ si ti a nrin loju ọna, A mọ pe Ijọ ibu ko ni Ẹdara.

Mr. A. D. Preece, Ọga Agba awọn *Niger Company* ni ilẹ yi, Akikanju ọkunrin gba isinmi lọ si ile, o fi Abẹokuta silẹ ni ọjọ 9 oṣu *October* yi, o si wọkọ "*Appam*" ni ọjọ 10 ọkọ a refo o.

Mr. Loman igbakeji ọga agba ti Eko ni o wa dipo Mr. Preece. A gbọ pe ọga agba yi yio wa ni Abeokuta titi di *December*, nigbati ẹniti yio rọpo yio de.

Mr. H. R. Routledge ati Mr. B. V. Hodder awọn ọga agba ti *Firm Niger Company* ti Eko bẹ ilẹ yi wo ni ọjọ 14 oṣu yi na, nwọn si wọ ọkọ *Motor* lọ si Ibadan ni ọjọ 15.

A gbọ pe *Agent* A. J. Tangalakis (Mr. A G. Leventees) ti o ti gba isinmi lọ si ilu rẹ, yio de si ilẹ yi ni ọjọ 17 oṣu yi, nigbati Mr. A. G. Lainas ti o ti dipo rẹ yio pada lọ, a ki Mr. Leventees o ku abọ, o ku ewu ọkọ.

KEKERE ẸGBA.

---

## BIRTH.

Mr. S. B. Mustafa of Obadina St. Lagos, begs to return thanks to all those who have been so kind as to honour his invitation to an At-Home on the 18th instant in honour of the naming ceremony of his new child—Miss Anotu Mustafa.

The following deserve special mention: Messrs: Springer, Lynch, Maye, Peter Jones, A. Kayode, B.L., Ayo Williams, B.L. Fasanu, B. A. Mumuney, and a host of others.

---

## A DUPẸ ỌJỌ.

Iya afin Madam Diamina Silva (Awẹlẹwa) Iya afin Mrs Theodore Harding (Ibadi-aran) ati Iya afin Miss Ayọ Labinjọ (ọpẹlẹngẹ) ati gbogbo Ẹbi dupẹ atọkanwa lọwọ awọn Ẹgbẹ ati ọgba ati awọn aimọye enia miran ti nwọn wa ba wọn daro lorişirişi ọna nipati arabinrin wọn Mrs Angelina Labinjo, ẹniti a pe lọ s'ọwọ ọtun Baba ni *Thursday* ọjọ kẹrindilogun oṣu yi, ni ile rẹ 28, Luther Street. Eko.

---

# STOP PRESS!

## The Herbert Macaulay Diamond Jubilee Celebrations.

At a fully representative Public Meeting held at the Glover Memorial Hall on Thursday last the 23rd instant on the invitation of Professor Deniga Editor *Eko Akete*, and presided over by A. Ade. Oṣodi Esq., Merchant, to consider the advisability of celebrating in a befitting manner, the 60th year to which Mr. Herbert Macaulay, C.E. will attain, on the 14th proximo in appreciation of his devoted and unstinted public services, it was unanimously resolved that the proposal be approved of and that step should immediately be taken to enlist the sympathy of the Nigerian National Democatic Party in the movement, having regard to the shortness of the time. Among those present are:—

The Hon. J. Egerton Shyngle Barrister-at-Law, First Lagos Member, President the N.N.D.P.; Mr. J. Bagan, Benjamin, C.E. one of the joint Secretaries N.N.D.P.; Hon. Prince K. Ata. Amonu Barrister-at-Law; Member for Calabar; Dr. Oguntola Ṣapara I.S.O.; Adedapo Kayode Esq. L.L.B. Barrister-at-Law.; Ayo Williams Esq. Barrister-at-Law; D. A. Leigh Esq. of H. M. Customs; Messrs D. Ayo and E. A. Olu. Bright, H. A. Phillips, Bamkẹfa Ọjọmu, all of the Nigerian Railway E.B.; J. A. Fakolujo of the Marine, Mr. Arinola Ọkọya Trader, Pastor Arinola Ibaru of J. H. Doherty, Mr. Alfred Williams of the C.W.S. Mr. S. A. Johnson of P.W.D.; R. A. Staveley Esq. Superintendent P. and T.; E. A. Ogunmoyero Esq. of Phillips Medicine Store, G. D. Francis Esq. of Bull West African Line, T. F. Olukotun Esq. Trader, George I. Phillips Esq. of the C.M.S. Grammar School, N. S. Ṣolade of Government Printing Office, Isaac B. Thomas Esq. representative of the *Eleti Ọfẹ*, Mr. E. M. Awobiyi of Elder Dempster & Co. Ltd., Kasumu Gbalaja The Başọrun, Kasunmu Ayorinde, Mumuney Animaṣaun, Disu Laniyan, Mesdame Saamota Ikẹ Ọlọrun, Kaliatu Kẹhinde Lika Ọloja Obinrin, and a host of others. Mr. John A. Tade Bright kindly acted as Recording Secretary.

Dr. Ṣapara in his fervent and persuasive speech at the meeting, actually took the cake for Yoruba oratory on the occasion.

A fuller report will appear in our next issue.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

**ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI** na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria,

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmałọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ orişi-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Şabu rẹ tabi ki o kọwe ranşẹ si ki o fi sọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọba P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

---

### Coftins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Remcvable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

**Cable Address :—**

"Steinafrik" HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neurwall 16/18**

**Hildebrandhaus.**

*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

3, DOSUNMU STREET.

---

### Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

DURO THOMAS,

55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**

**Highly Recommended:**

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**32s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

ILU ẸPẸ KO KERE L'AWO, EIYẸ O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ti No. 88 Opopo nla l'Eko nibi ṣẹṣẹ ṣi Ile Egbogi to kẹriri kan si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Ọja awọn Oyinbo Oniṣowo John Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajaloḷẹru Egbogi ni Ṣabu na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹrẹ ti a ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo: bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.

## T. A. Erinosho,

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent, Produce Merchant. Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242, Lagos, Nigeria.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orişirişi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orişirişi, ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.